# IROHIN IMỌLẸ

ỌMỌLẸ ỌRE AIYE. TẸNI GBOGBO LA WA

No. 578 MONDAY APRIL, 13 1964 (2D)


## Obinrin Kan Le Ọkọ Rẹ Jade N'ile

ẸKO:— Ẹrin ni awọn ero ti nwọn pejọ si le ẹjọ giga kan ni ilu Eko nrin bi Ọgbẹni Andrew Amechi Melic ti ṣe ọga agba kan nile iṣẹ Ijọba Apapọ Naijiria ti bẹrẹ si rojọ wipe, Ọlọrun lo yọ mi ti nga fi ku nigbati iyawo mi fa ada yọ ti o si le mi jade ni ihoho ọmọluwabi ti mo si ba oju ferese fo jade lati sa asala fun ẹmi mi.

Ọgbẹni Melic yi nro ẹjọ lati le ṣe ala ye iru iwa buburu ti iyawo rẹ nhu si i' ki o to pe ẹjọ ikọsilẹ.

O tun fihan ile-ẹjọ wipe ninu oṣu kẹ ta ọdun 1956, iyawo on na kọ jalẹ lati tọju onjẹ silẹ fun on.

Ṣiwaju si i, Ọgbẹni Melic fihan ile ẹjọ wipe oninu fufu ni iyawo on, ki si ṣe ẹniti o ngbọran si enia lẹnu, o si tun feran lati ma a huwa abuku ati afojudi si enia.

O tun sọ wipe ọpọlọpọ igba ni ọmọ ọdọ ti o wa lọdọ on ma ngba on silẹ lọwọ iyawo on bi ija ba ti de.

O ni ni ọjọ kẹwa oṣu keje ọdun 1957 ni iyawo on da omi gbigbona si on lara ninu ile nigbati awọn nja.

O tun fihan ile ẹjọ wipe ni oru ọjọ kan ninu ọdun 1958 ni iyawo on tilẹkun mọ on ti o si bẹrẹsi lu on bi ẹjọ aijẹ ti ko tilẹ jẹki on lọ si ibi iṣẹ ni owurọ ọjọ keji.

Ọgbẹni Melic tun fihan ile ẹjọ wipe ninu oṣu kẹfa ọdun 1961 ti on pẹlu iyawo on lọ si ilu Oyinbo larin ilu Londọnu ni iyawo on ti bẹrẹsi doju ti on

Wo Oju Ewe Kẹfa

# AGBẸJỌRO AWOLỌWỌ PE ADAJỌ NI IJAKADI!

## Awọn Ọlọpa Duro Gba-gba Yi Ile Ẹjọ Ka

Ọgbẹni Victor Durand, Oloye Amofin ti iṣe Agbẹjọro Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre, sọ fun Ile ẹjọ gigajulọ ni opin ọsẹ ti o kọja yi, pe awọn ko gbọdọ fi idajọ Ile ẹjọ giga silẹ laipe ni ijakadi ki o ma a ba ṣe ba oruko rere, tabi ta amin abawọn si Oloye Awolọwọ lara.

Ọgbẹni Durand ṣe alaye fun Ile ẹjọ pe, ọkan ninu ẹsun ti adajọ Ile ẹjọ na fi ju Oloye Awolọwọ si ẹwọn ọdun mẹwa jẹ ohun ti o le ṣẹlẹ si ẹnikẹni lẹhin ọla.

Gẹgẹbi alaye rẹ, Ọgbẹni Durand sọ fun Ile ẹjọ pe, arẹ ọkan on irẹwẹsi de si Oloye Awolọwọ nigbati ẹgbẹ rẹ Afẹnifẹre kuna lati moke ninu ibo Apapọ, ti ọdun 1959.

Ọgbẹni Durand ni iru ohun ti o ṣẹlẹ si Oloye Awolọwọ nigba na yio ṣẹlẹ ni Ilu Oyinbo laipẹyi Eyi ti aiye o gbọ ti ọrun o si mọ.

O ni, nipa awọn ẹlẹri ti o wa jẹri ni Ile ẹjọ, fun Ijọba o ni o jẹ ohun ẹdun ọkan pe adajọ Ile ẹjọ giga na gba ẹri Sanya Ọnabamiro Minista Alamojuto awọn ohun ọgbin fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria gbọ, ti o si kọ ẹri Dọkita S A Aluko.

Ọgbẹni Durand wa sọ fun Ile ẹjọ pe, on ko fẹ ki awọn adajọ ile ẹjọ giga julọ kọ ibi-ara si ẹri Dokita Sanya Ọnabamiro, ti o wa jẹri ni ile ẹjọ nipa Igbimọ Ọlọgbọn ori.

O wa bere pe, "Bawo ni Dọkita Ọnabamiro ṣe le jẹri nipa Igbimọ ẹgbẹ Afẹnifẹre nigbati ko si ninu Igbimọ na, ki iṣe ọkan ninu wọn, ko si ba wọn se ipade, kini O mọ ti nwọn se ninu ipade?" oni ọrọ "nwọn ni" ni Dokita Ọnabamiro wa sọ fun ile-ẹjọ, ko mọ ohun ti o ṣẹlẹ ninu ipade na"



## Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

O ni o wa jẹ ohun iyalẹnu pe lori ẹri ti ẹniti ko si nibi ọkan jẹ, ni adajọ fi i ṣe idajọ rẹ.

Ọgbẹni Durand tun ṣe alaye pe ko si ọkan ninu iwe ti Oloye Awolọwọ kọ, ti o fi han pe o fẹ doju Apapọ Ijọba bolẹ, ki o si fi ipa gba Ijọba.

Oniwe Irohin wa, Ejon gboro fi ye wa pe, awọn adajọ Agba marun lo wa lori aga ijoko. Awọn adajọ na ni. Ọlọla Adetokunbọ Ademọla, Olori gbogbo awọn adajọ Agba fun Apapọ Ijọba Naijiria, (Alaga) Ọlọla Conrad Taylor, Ọlọla Louis Mbanefo, Ọlọla Lionel Brett ati Ọlọla Vake Baisamian.

Awọn agbẹjọro mẹsan ni o ngbẹnuṣe fun Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Oruko awọn mẹsẹsan na ni wọnyi. Ọgbẹni Victor Durand (Olori), Ọgbẹni M. O Ọdẹsanya Ọgbẹni M. A. Adesanya, Ọgbẹni Olu. Ayọọla, Ọgbẹni Yinka Ayọọla Omidan Bisi Adebule Ọgbẹni S. F. Ọlakunrin Ọgbẹni T. O, Kellock, (ti iṣe Oyinbo) ati Ọgbẹni Efueye.

Awọn enia mẹrin ni Agbẹjọro fun Ijọba ti yio tako ẹjọ awọn enia. Oruko awọn mẹrẹrin na ni wọnyi. Ọgbẹni Duro Adebiyi Olori Ọgbẹni B. O. Kassem, Ọgbẹni A. Adebayọ ati Ọgbẹni Iyalla.

Ninu ile ẹjọ na, mo ri diẹ ninu awọn olori ẹgbẹ Afẹnifẹre, awọn bi Ọgbẹni Julius Adeọla Ọdẹku akọwe agba fun ẹgbẹ Afẹnifẹre, Oloye Akin-Olugba d.e. Ọlatunji Dosumu, ati ọpọlọpọ awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ ninu ile Igbimọ Ijọba Ibilẹ Eko

Nigbati mo wo gbogbo ile ẹjọ na yika awọn obinrin mẹfa pere ni awọn ọlọpa gba laye pe ki nwọn wọle, ninu wọn ni mo ti ri Iyaafin Jakande, onigegewura.

Nigbati mo fẹ wọ inu Ile ẹjọ na mo fẹrẹ ya igbẹ si ara, nigbati mo ri awọn Ọlọpa pẹlu kondo lọwọ wọn ti nwọn duro ni ẹnu ọna ti nwọn si le oju koko si mi bi mo ti fẹ wọle.

Gbogbo apo awọn ti o nwọle ni awọn Ọlọpa nwo, Ọkurin kan ti o tẹle mi, ni awọn Ọlọpa dapada nigbati nwọn ri atupa ina siga ninu apo ẹwu rẹ.

Ọga awọn Ọlọpa ni Ọkunrin na le fi atupa ina siga rẹ ṣe ohun Ọṣẹ ninu ile, ṣugbọn Ọkunrin na ju atupa ina siga rẹ nu, ni awọn Ọlọpa ba jẹki o wọle.

Enia diẹ ti nwọn ni iwe aṣẹ lọwọ ti nwọn ko si mu ohun Ọsẹ lọwọ ni awọn Ọlọpa gba laye lati wọle, nwọn si le gbogbo awọn ti ko ni iwe lọwọ pada.

Awọn olujẹjọ mẹtala ni nwọn wa si kotu ninu nwọn ni: Jakande ati ọgbẹni J. S. Ọlawọyin, awọn yoku ko wa. Nṣe ni awọn ọlopa duro gbagba yi gbogbo ile ẹjọ na po pẹlu olutọjn awọn ẹlẹwọn.

Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ funra ararẹ ko wa si Ile ẹjọ ni ọjọ na, ṣugbọn alero pe yio wa ni owurọ yi.

Nigbati Ile ẹjọ na yio tun ma ba ipade wọn yoku lọ.

Bi nwọn ba ti sọ ọrọ na si ni kotu ni owurọ yi, ẹ o ma gbọ ni owurọ ọla.



Ọgbẹni Adedipẹ

# Are 'Afọtẹjo-ye' Dun Pupọ

Ona mẹta pataki ni nwọn pin ere na si, ere na si bẹrẹ pelu orin etiyeri, gbogbo ọmọ Yoruba ni o mọ egungun ti o njẹ etiyeri bi o ti mọ orin Ọtẹ kọ to ati bi o ti tun mọ enia yin daada, Egungun yi kọ ọkan ko jọ kan orin, ojuba onile, o tun juba alejo pẹlu.

Ọbalọwọ ni ọba ilu Jontolo, Ọlaọrẹ si ni igba keji rẹ, lẹhin Ọlaọrẹ, babakindele ni awọn Ijoye miran bi Osangbetọ, Adeaka ati Oyebode wa

Fadẹkẹmi, iyawo Ọlaọrẹ ni o kọkọ ẹkun sinu pe, gbogbo anfani na lo nlọ si ọdọ iyawo Ọbalọwọ, gbogbo ola ti o tọ si Ọlaọrẹ, ọdọ Ọbalọwọ ni o tun nlọ, iya ni on ati ọkọ on njẹ, bi ọkọ on ati oloye Oyebade ba ṣegun gbogbo iyi ati ẹyẹ ọba ilu ni lo ngba, nitorina inu iyawo Ọlaọrẹ ko dun si rara.

Ni Ọlaọrẹ ba mura lati ditẹ si ọba ilu Jontolo pẹlu awọn Ijoye die. Awọn enia na ni afi ki awọn o yọ Ọbalọwọ lori oye ni awọn yio to gbadun.

Ni ogun ba bẹ silẹ larin Ọlọtẹ ọba Bọtẹ ati Ọbalọwọ ọba Jontolo ni awọn ara Jontolo ba ṣẹgun ilu Bọtẹ. Ọlaọrẹ ati awọn Ijoye ni ojagun nla na, ṣugbọn Ọbalọwọ ni nwọn nfi iyi ati ẹyẹ fun, eyi tun bi Ọlaọrẹ ninu pupọ.

Apakeji tun bẹrẹ pẹlu orin ayọ iṣẹgun, awọn ọkunrin ati obinrin tun ko ara wọn jọ nwọn korin pe, Ọbalọwọ rora mọ bọ, rora mọ bọ Ọbalọwọ ṣegun abuse buse, eniọla ṣẹgun abuse buse, ogun ko si mọ, gidigbo ko si mọ, eniọla segun abuse buse.

Orin yi wa run Ọlaọrẹ ninu ati oloye Osangbetọ ni nwọn ba pa imọpọ lati ditẹ si Ọbalọwọ, nwọn yọ lori oye. Ni Oyebode ba lọ ba Ọlaọrẹ lati bere ọtẹ kikan, oloye Osangbetọ gbee lẹhin.

Awọn kan wa ayọ, nwọn si nsọ iwa ibajẹ to wa larin awọn Ijoye ati iru ẹtan ti nwọn ntan Ọlaọrẹ.

Ọbalọwọ so fun iyawo re pe on 'a ala nla kan ti nba on leru, lọgan ni Oyekan iyawo rẹ dahun pe, kabiyesi emi na mala ala nla kan ti o nkọ ni lominu Iyawo na ni on ri Orunba Oloye Ọlaọrẹ ti ofi okun si nyin lorun ti a nyin fun Maalmu kan ti o wa mu ọrẹ lọwọ ti o fi na nyin, nigbati e de ibikan ti ẹ o lọ mọ, o bere si na nyin lọrẹ gbogbo enia nfi nyin rẹrin.

Etiyeri tun wa sere, nwọn tuda orin fun wa ni awọn joye ba jọ ko pẹlu Ọbalọwọ ni ohun jẹ karonu, gbogbo ilu nyin mọ dara, ko si ifọkan Balẹ e duro ejẹ karonu.

Ọbalọwọ ni on yio gba ọpa oye lọwọ Ọlaọrẹ ni awọn kan ba nbẹ Ọbalọwọ, o ni awọ fẹlẹfẹlẹ bonu, ko jẹ kan ikun aseni, aiye tiri bi fọn ran owu osi tun nipọn ju eti erin lọ. Ni Oloye Osangbetọ ba ni ki Ọlaọrẹ ko mọ bẹ Ọbalọwọ ko nṣe Ọlọrun ni Ọlaọrẹ dọbalẹ o nbẹ Ọbalọwọ.

Ṣugbọn ko gba o ni ki o mu ọpa oye wa 'lọla.

Ni Ọbalọwọ ba gba ọpa oye lọwọ Ọlaọrẹ ni Ọlaọrẹ ni Hawu! Bi aba bẹ egungun, egungun a mọ jẹ bi a ba si bẹ orisa asi mọ gba bi a ba bẹ Ọlọrun Ọba a mọ darijin, nigbati Ọbalọwọ ko gba emi na yio taku emi na yio se ni suta.

Ọlaọrẹ lọ ba Ọlọtẹ nwọn gbimọ pọ sugbọn Ọlọtẹ ko fẹ gba a gbọ ni nwọn ba mulẹ Ọlaọrẹ to Oloye Osangetọ lọ o sọ gbogbo ọrọ na fun Osangbetọ ni on ko fẹ ogun ni ti on.

Ọlọtẹ ti ṣe ileri pe bi Ọlaọrẹ ba ran awọn lọwọ ti awọn ṣẹgun Jontdo awọn yi fi Ọlaọrẹ joba. Pẹlu iran lọwọ Ọlaọrẹ Ọlọtẹ ṣẹgun ilu Jontolo nwọn si Ọlaọrẹ joba ilu Jontolo ni awọn Obinrin tun nkọrin, Ọlaọrẹ ṣẹgun abusebuse baba Dele sẹgun abuse buse, kin le rfọba pe ati bẹẹbẹ.

Lẹhin na ni nwọn ba mu Ọbalọwọ Ọba Jontolo wa

pẹlu ẹwọn lọwọ are na arinrin ẹniti o kọ ere idaraya na ni Ọgbẹni Afọlabi Olabimtan ẹniti o nkọ awọn ọmọ ile-ẹkọ ti o njẹ Methodist Boys High School.

# YẸYẸNATU!

## ONIYẸYẸ EKO

Yẹyẹnatu:- Olotu, mo fẹ ṣire kan lọjọ mẹdogun.

Olotu: Iru ere wo niyẹn, Ṣe ki i ṣe "Yoruba Ronu"

Yẹyẹnatu:- Rara, Akintola ronu ni

Olotu:- Ha! tani ma a wo? Nibo lo ti fẹ ṣe e?

Yẹyẹnatu:- Mo fẹ kọkọ ṣe fun N.N.D.P. ni Ibadan.

Olotu:- Ntori kini?

Yẹyẹnatu:- Ṣe e mọ pe Ẹgbẹ ọmọ Olofin ni Ogunde kọkọ ṣe "Yoruba Ronu" fun

Olotu: Yẹs kẹ, iyẹn ye gbogbo wa, Se Ogunde nfẹ ki awọn Yoruba ronu kuro ninu iya ni.

Yẹyẹnatu:- Bẹni emi na nfẹ ki Akintọla ronu ki ilu ba le toro ni.

Olotu:- Bawo?

Yẹyẹnatu: H ha, ẹyin ko si rilu ni tabi ẹ ko gbọ rudurudu ti ma nbe silẹ nibikibi ti Akintọla ba de

Olotu:- Rudurudu kẹ

Yẹyẹnatu:- Adirudurudu

Olotu:- Howu, o ju ti Ilẹṣa ti a gbọ yi na lọ ni ?

Yẹyẹnatu:- Kekere ni ti Ilẹṣa Ẹnyin ko gbọ ti Ilaro ni

Olotu:- Kilo ṣe ?

Yẹyẹnatu:- Ha! Ti ilu daru ti Akintọla fo jade ti on na ngba ija awọn ọmọ ogun rẹ ti nda ilu ru ja.

Olotu:- Lootọ?

Yẹyẹnatu:- Iyen nikan ni. Ti Akiutọla tun ba Ọlọpa ja, to titori pe Ọlọpa mu awọn ọmọ ogun re ti nda ilu ru ti o lẹgbogbo ọlọpa sita, to si ti ile ọlọpa.

Olotu:- Wi kin gbo!

Yẹyẹnatu:- Tabi ẹko gbọ ? Ti Akintọla tun jẹ Ọba Ilaro ni iya o ni nitori pe ko bọ ewu ki oma ja fun on

Olotu:- Nko le gbagbọ ṣa nitori gbogbo Ilaro ni a gbọ pe o ti di ẹgbẹ ọlọwọ nisisiyi

Yẹyẹnatu:- Irọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ Akintọla npa kiri ni yẹn Ẹ wo o ti ko ba si nkan to ṣẹlẹ ni Ilesa irọ ni nwọn iba tun pa

Olotu:- Ṣugbọn kini ṣe ti ko wadi tan ki o to ti ile-iwe ti o si tun yo oga ile iwe ni iṣẹ

Yẹyẹnatu: Ani ki Ọlọrun jẹ ki Akintọla ronu Bi o ba ronu ko ni maa gba ete kiri O lọ si Ijẹbu, nwọn tori tire ko awọn Ọmọ ile-iwe kekere de kootu, o lọ si Ilẹṣa, nwọn tori re ti ile-ẹkọ giga. Akoko Akintọla wa le koko, oburu oju ata ninu oja, Ṣugbọn bo ba ronu ṣe adara.

Olotu:- Ṣe gbogbo ohun ti ofẹ fi ṣe ere na ni yi?

Yẹyẹnatu:- Yes ke! Mo fẹ ki ẹwa wo Akintọla bi oṣe fi ọtẹ di oga, bi oṣe nfagbara mu enia lati ṣe tirẹ, bi osi ṣe nda rudurudu nrin ilu kiri

Olotu; Bawo lo ṣe mọ

Yẹyenatu:-Bowo ni on ma pe awọn kan lo nda ru duru silẹ? enia meji njo ọkan ninu awọn mejeji fi ara rẹ se adajọ Tani ko mọ pe adarudurudu ni.

Olotu:- Emi ko mọ iyẹn

Yẹyẹnatu;- Nje bi o ba jẹ ẹniti nwa irẹpọ wa a ma a bu Awolọwọ ninu radio? Ewo ha tun ku ti ẹ fẹ ṣe Ẹronu sir

Olotu:- Wo ma ko ti ẹ ba mi o ma lọ, o dabọ


# AKARA TU S'EPO!

## Iwe Itumọ Ala na ti de !!

Eyi ni lati kede fun awọn onkawe Irohin Imọlẹ pe Iwe Itumọ Ala lati ọwọ Joseph Alala ti jade fun tita nisisiyi. Iwe Ala yi yatọ si Iwe ala miran nitoripe Odu Ifa ni nwọn fi tumọ rẹ Egbogi jaburata si wa ninu rẹ pẹlu. Tete ra tirẹ ki o to tan.

Iye Owo:— Iwe kan 5/-
Dọsini 36/-

J. O. SHOYINKA
N2/99 Shittu Street
Ibadan

# Awọn Ọmọ Ogun Ilẹ Naijiria Ti Bẹrẹ Iṣẹ Ni Tanganyika

DAR-ES-SALAM:- Pẹlu inu didun Ijo ati ayọ nla ni awọn ara ilu Tangayika pataki julọ awọn ọmọ ẹgbẹ ti nṣe Ijọba TANU fi pade awọn ọmọ ogun ilẹ Naijiria ni ebute ọkọ ofurufu.

Ẹniti oṣe olori fun awọn ọmọ ogun na ni Major Okorie ọkọ ofurufu ti ilẹ Naijiria ti nwọn ṣẹṣẹ ra ni nwọn ba lọ si ọhun (Fokka Friendship) Ọmọ ilẹ wa kan ọgbẹni Orimalaye ni o wa ti ọgbẹni Hayes şişe atọna rẹ.

Bi ọkọ ofurufu yi ti gunlẹ ni ilu Dar-es salam ni Ọgagun ti oko.........

awọn ọmọ ogun na lọ sọkalẹ ti osi paşẹ ki gbogbo awọn ọ m ọ ogun na lo n i ọwọwọ ti nwọn s i ki Asoju ilẹ Naijira ọgbẹni N. Ade Martins lẹhin na ni o wa tun fi awọn ọmọ ogun na han Alakoso fun eto o g u n ilẹ Tanganyika Ọlọla Kambana.

Ọlọla Kambana sẹṣẹ wa fi awọn olori ijọba ilẹ tirẹ han gbogbo awọn ọ m ọ ogun na.

Irohin fi ye wa wipe, Iru ọna ti nwọn fi yọ a y ọ nla fun awọn ọmọ ogun ilẹ wa yi jẹ iyatọ ati p e o fi han ọna ifọwọsọwọ pọ yio wa larin orilede mejeji

# Gbanjo o !

Eyi ni lati kedefun gbogbo awọn ONIBARA wakọ jae Jado agbaiye pe ac bẹresi ma a ta Ọja gbanjo wa fun ti Ọdun EASTER ati ILEYA gẹgẹbi iṣe wa lọdọọdun Ohun ti o tun mu wa tete bẹrẹ gbanjo yi ni pe, iwe ti, o nti ọdọ awọn ONIBARA wa wa lati:-

**Ghana, Abijan, Cotonou, Lome ati Portnovo**

Ko ni'ye pe ki a tetebẹrẹ GBANJO na.

TETE WA RA TIRẸ LONI

ỌJA GBANJO NA BẸRẸ LATI 2?th MAC.-30th APR

Iwe Egbogi Ajebidan 25/— di 22/6d
Iwe Ilana Ifa, Iyanrin tite Etutu şişe 21/- di 18/-
Iwe Afọsẹ Isẹdalẹ Yoruba Psalm Isẹgun Ajẹ 4/6d di 3/-
Iwe Ala Nla 7/6d di 5/6d
Iwe Ala ati Iwadi Nkan 2/6 di 2/-
Turari Isẹgun Ajẹ 10/6 di 8/-
Certificate of Appreticeship 7/6d di 5/-
Tailor's Measurement Book 7/6d di 5/6d
Iwe Itan Ala 2/6d di 1/-
Iwe Itumọ Ami Ara 4/6d di 3/-

AKIYESI:— Ẹnikẹni ti o ba ra ninu awọn ọja yi yio gba TURARI IŞẸGUN AJẸ" lọfẹ lati fi dan wa

**Shoyinka**
2/99 Shittu Street
Ibadan

# YE IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Işẹ rẹ nfẹ amojuto ni pataki ki o ma ba ni abawọn, nkan iyanu kan yio desi ọ lojiji' Ẹnikan yio wa tọrọ ohun kan lọwọ rẹ nitori na, moşe şahun.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Gbogbo işẹ ti o ba şe pẹlu enla gigun yio mu orire dani şọra rẹ, ki o ma ba padanu nipa ijafara.

ARIES (Marh 21-April 20) Ọrọ ija farahan siọi ayafi bi o ba le ko ija silẹ, ki ọkan rẹ le balẹ. Aşalẹ ọjọ oni yio rọrun fun ọ ti iwọ yio si gbagbe gbogbo wahala rẹ

TAURUS (April 21-May 20) Maşe ba ẹnikẹni şe ọrẹ loni ki o ma ba da ọ, nitoripe awọn ọrẹ ti o ni, ko ngbọnran. Ibikan ti o fẹ lọ, nwọn ko ni jẹki o lọ sa ma rẹrin

GEMINI (May 21-June 21) Ko nşe ohun to dara fun lati ma tọ ọna kan şoşo lọ. Fi ọkan balẹ, ki o si ronu, mura lati din gbogbo gboke gbodọ rẹ ka, maşe kanju lati ra nkan.

CANCER (Jun 22-July 23) Odara ki o ma ronu wo ki o to gbe ọkan kuro ninu ohun kan nitoripe ni akkoko ọjọrọ nigbati ori rẹ ba wale, ki o ma ba jẹ nkan iyanu fun ọ.

LEO (July 20-Aug 22) Gbẹkẹle ọrẹ rẹ kukuru kan şugbọn fun igba diẹ ni, owo le sọnu lọwọ rẹ loni.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Işẹ ti o ba dawọ le loni, ere pupọ yio wa nibẹ. Mu ileri rẹ şẹ ion awọn alabagbe rẹ nkan ti o ngbero lati lati şe, ko le ba ode pade ni akoko yi.

LIBIRA (Sept 24-Oct 23) Irẹpọ rẹ pẹlu ẹlomiran ko dara loni, jẹki o di ọjọ miran, maşe sọrọ lile pẹlu enikẹni ki ijọrfọn ma bẹ larin iwọ ati ọrẹ rẹ obinrin

SCORPIO (Oct. 24 - Nov. 22) Bi o ba ni oniranlọwọ loni obara to gbajẹ, şugbọn logbọn bi ejo, ki o si niwa tutu bi adaba. Iwọle ba obinrin ta loni şugbọn şora ki oma ba ru bedi

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 22) Tọju işẹ tọkantọkan, iwọ yio si gbọ irohin kan ti ko dun mọ ọ ninu maşe banujẹ.

CAPRICORN (Dec. 23 - Jan. 21) Bi ọna kan wa ti ofi le ri o-o eyi ni akoko na.

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANŞE TI NWỌN NPE NI-

**RICHALET**

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO

Eleyi yato patapata si awọn Rọbi-rọbi. Isẹ rẹ lara eni si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro-buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọnmọnọ




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nti kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di o w o Iyẹn şe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni lẹ yi,

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba awọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranşẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Tatambulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju şuşu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ ba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalap Egbogi-Eş Amodi Apo ile ilọ, ẹhin didun tabi baradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogi kokoro buruku ti o wa nba ẹjẹ ara rẹ patapata yio si ni ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹ u.

Şa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street ( Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji)

(2) Adedun Chemist
4 Wakeman Street, Yaba

# Eyi ni awọn ọjọ Ọja Ilẹ Yoruba

## ỌJỌ AJE APRIL 13 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ. | Mushin, Badagary |
| ABEOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omida Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonkọ, Tọwọbowo Temidire |
| IJEBU | Ikẹnnẹ, Ọkun—Ọwa, Ẹruwọn Omu Mamu |
| IJESHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| EGBADO | Igbogila Ijọun, Imasai Owode |
| EKITI | Oke-Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ IṢẸGUN APRIL 14 (TUESDAY)

| ILU | ILU |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ . | Ikẹja, Agege, Ebute-Ero Ọjọ Ajido |
| ABẸOKUTA | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọla Ajegunlẹ, Idọgọ Olodo |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunlẹ Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imodi |
| JẸSHA | Iwara, Ejiro, Odo, Ibokun, Lasilo, Idiẹmi |
| ẸGBADO | Okemesi Ifaki |
| EKITI | Ijẹbu-Ijẹsha |

## ỌJỌ'RU APRIL 15 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo |
| ABẸOKUTA | Ijoko Ibẹrẹkodo, Asu, Wasnimi, Owode |
| IBADAN | Akẹroro, Idọfin, Lagun, Sagbẹ Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU | Aiyepe, Sagamu, Itaosu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Rẹmọ |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdan, Sunwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ APRIL 16 (THURSDY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye |
| ABẸOKUTA | Atan Agbado, Ifọ Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila, |
| IBADAN | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ogburo, Ẹgbẹda Babalokuta, Ijaiye Orile. |
| IJẸBU | Ilishan, Isara, Imodi. |
| IẸSHA | Ẹpe, Ilọba, Imuroko, Erinmọ. |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado-Oda. |
| KITI | Egosi, Odo-Aiyedun. |

## ỌJỌ ẸTI APRIL 10 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodẹkọ Omida Itwọ |
| IBADAN | Itoko, Ṣojukonko Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikenne, Ọkun-Ọwa Eruwọ Omu Mamu |
| IJẸSHA | Oshu Itagun, Odogbo Idoko |
| ẸGBADO | Iloko |
| EKITI | Igbogila, Ijọun, Imasai, Owode Oke—Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ ABAMẸTA APRIL 17 (SATURD Y)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikẹja, Agege |
| ABẸOKUTA | Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajọl Ajegunlẹ, Idọgọ, Olodo. |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunle, Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imọpe |
| IJẸSHA | Iwara Ejiro, Odo, Ibokun Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilo-Idiẹmi |
| EKITI | Okemẹsi, Ifaki. |

## ỌJỌ AIKU APRIL 18 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo, Ejinrin |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Bẹrẹkodo, Aṣu, Wasinmi, Owode |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun Ṣagbẹ, Ogunjau, Mọlete, |
| IJẸBU | Aiyepe, Shagamu, Itaoṣu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Rẹmọ, Oyingbo |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi-Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdua, Sunwa, Iboro, |
| EKITI | Ilogbo, Ishan. |

## ỌJỌ AJE APRIL 19 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye,Ikosi, Ẹpẹ |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila |
| IBADAN | Fẹdẹgbọ, Oyedeji, Ẹgbẹda, Babalokuta' Ijaiye-Orile |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe ṣara, Imodi, Ishan, Akẹsan, |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọo Ilaṣẹ, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado-Odo |
| EKITI | Egosi, Odo-Aiyedun |

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

Lati Ọwọ EJO'NGBORO

### IKOYI

Jinnijinni dabo gbogbo enia nigbati ọkunrin kan, Robert Nyak duro si ẹgbẹ ile iyagbẹ ni nọmba 19, Cooper Road,ti o si ṣubu lulẹ ni ogedengbe ti o si fi bẹ ku bamubamu.

### SURULERE

Ariwo ta gee, nigbati mọto, nọmba N. N. 12 kọlu ọkunrin kan ni opopo Westetn Avenue Awọn ọlọpa ti gbe ọkunrin na lọ si Igbobi fun itọju.

### IJỌRA

Idaamu nla ba gbogbo enia ti owa nitosi nigbati ọkunrin kan Fọlarin Odu-Banjoko ti o ngbe nọmba 22, Akinwunmi Street, lọ si Ijọra ti awọn ọlọṣa gbe alupupu (onigẹgẹ lọrun) rẹ Nọ L H 1732 lọ.

### YABA

Ariwo ta ge e, nigbati mọto ayọkẹlẹ kan nọmba L.G1034 kọlu ọmọbinrin kan Ọmọbọla Ọdunlami ti o ngbe 23, Ibikunle,street, wọn ti sare gbe ọmọbirin na lọ si Igbobi.

### EKO

Gbogbo enia bẹrẹsi gbọn t.ti bi igbati alupupu ti o bajẹba fẹ gun ori oke nigbati ọmọbirin kan Rafiatu Alabi ṣubu lulẹ ninu iyara ni nọmba 24, Ẹyin-Iga ti ọmọ na si ku bamubamu.

### EBUTE-MẸTTA

Ariwo ẹkun ta ge e, nigbati igi gẹdu nla kan wolu ọkunrin kan, Karimu Ṣannsi molẹ ni nọmba 1 Ọsholake Stleet. Bi nwọn, ti gbe igi gẹdu na kuro lori ọkunrin na ni o ba ku.

### IJỌRA

Idaamu nla ba gbogbo enia nigbati mọto ayọkẹlẹ kan Nọ L D 3867 kọlu obinrin kan tio ngbe nọmba 14, Ilajẹ Ijọra Oloye bi o ti fẹ sare kọja oju ọna' Nwọn ti gbe obinrin na lọ si ile iwosan.

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 578 MONDAY, APRIL 13, 1964 (2D)


## Awọn Adajọ Meji Di Adajọ Ile Ẹjọ Giga Julọ

EKO:- Arẹ ilẹ Niajiria Ọlọla Dokita Nnamidi Azikiwe fi awọn adajọ Agba meji jẹ adajọ ti ile ẹjọ giga. Awọn Adajọ meji na ni Ọgbẹni Chike Idigbe ti ile ẹjọ giga ti Ila Orun Naijiria ati Ọgbẹni Michael Oguejiofo Ajegbo minista ala-mojuto eto ofin ni Ipinlẹ Ila Orun Naijiria lati jẹ awọn adajọ agba fun ile ẹjọ giga julọ ti Ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria ati Ilu Orun Naijiria lati ọjọ kẹsan oṣu yi.

Arẹ ilẹ Naijiria ni o fi awọn adajọ meji na bura gẹgẹ bi adajọ agba ni afin Arẹ wa, ninu ọsẹ ti o kọja yi,

Arẹ na tun yan Ọgbẹni Luis Mbanefo Olori Adajọ awọn agba ni Ipinlẹ Ila Orun Naijiria gẹgẹ bi adele adajọ agba ti ile ẹjọ giga julọ orilẹ-ede Naijiria lati ọjọ kẹsan oṣu yi. Abi Ọgbẹni Ajẹgbo ni ọjọ kini kẹwa oṣu ọdun 1921.

O si lọ si ile ẹkọ Dennis Memorial Grammar School, Onitsha, Unifasiti ti ilu Londọnu ati ile ẹkọ fun awọn igbimọ amofin Ọgbẹni Ajẹgbo di amofin ni ọdun 1947.

Awa onlwe irohin Imọlẹ ki nyin pe ẹ ku orire o, ọkọ ọba ko ni ṣa nyin lẹṣẹ o.

# ỌWỌ ỌLỌPA TẸ ẸNITI O NRIN LARIN ORU

EKO:- Ẹlẹri Ijọba kan, Ọgbẹni Nelson Akinde sọ fun ile ẹjọ kekere kan nilu Eko ni ọjọ Aje tiṣe ọjọ keje oṣu yi wipe ni oru ọganjọ ọjọ kẹrinlelogun oṣu kẹsan ọdun ti o kọja yi ni on gbọ igbe "Ole! Ole!!" ni eti ile ti on ngbe ni on ba sare jade.

Ọgbẹni Akinde tun sọ pe on nkọ iwe lọwọ ni on fi gbọ igbe na, bi on si ti jade ti on bojuwo ọgangan ibi ti nwọn ti nkigbe "Ole! Ole!!" ni on ba ri ọdọmọkunrin kan ti o nsare bọ wa si ọdọ on.

Oni bi ọdọmọkunrin yi ti nbọ wa, bẹni on ke ti o si sọ pe, "Ọkọ Bọsẹ gun mi lọbẹ".

Ẹlẹri Ijọba yi, Ọgbẹni Nelson Akinde jẹ oṣiṣẹ ibi iṣiro owo nile iṣẹ ile ifiwe ranṣẹ.

O njẹri si ẹsun meji ti awọn ọlọpa fi mba ọdaran kan, Rodrives Peters ṣe ẹjọ wipe o nrin kiri larin oru ati pe o tun fi ọbẹ gun Ọgbẹni Sigismund Ogunade ti o si da ọgbẹ si lara.

Ọgbẹni Akinde tun sọ fun ile ẹjọ wipe ki on to jade sode ni on ba tan ina lati le ri gbogbo ohun ti nṣẹlẹ

O ni bi on ti de ibi ti nwọn ti nkigbe ni on ba ri ẹsẹ bata meji ati adaku ọbẹ kan nilẹ

Ẹlẹri Ijọba keji ni ọlọpa Ọgbẹni Henry Abu o ni on jẹ ọkan ninu awọn ọlọpa ti o mu ọdaran na ni ọjọ na ati pe on ni o gba ọrọ kọ silẹ lẹnu ọdaran na

O ni ninu ọrọ ọdaran na ti o sọ lẹhin igbati ọwọ tẹ ẹ tan, o ni Ọdaran na ṣẹ jalẹ patapata wipe on ko mọ nipa iṣẹlẹ ti o ṣẹlẹ ati wipe on ko on ni ẹsẹ bata mejeji ti nwọn ri pẹlu aṣẹku ọbẹ

Ẹsun ti awọn ọlọpa kasi ọdaran na Rodrives Peters lọrun ni pe awọn fura si irin ẹsẹ rẹ larin oru ni iwaju ile kan ni nọmba 36 Ọbalende road ati wipe o fẹ lati le ṣe Ijamba ni.

Nwọn si tun lero wipe on lo lọ gun Ọgbẹni Ogunade ni ọbẹ ti o fi ṣe lẹṣẹ

Bi Adajọ ti ṣe Iwadi ọrọ yi lẹnu ọdaran na ni o ba gbọn ori rẹ ti o si ṣẹ kanlẹ ti o ni on ko jẹbi ẹsun ti nwọn fi kan on

Ni Adajọ ba sun gbigbọ ẹjọ na si ogunjọ oṣu yi

Bi nwọn ba ti tun ṣe ẹjọ na si ẹ o ma a gbọ o.


make it a successful SEASON with MERCEDES-BENZ TRUCKS

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.


### LATI OJU EWE KINI

ti o si tun kan on labuku ti o fi jẹ wipe on ko niyi loju gbogbo awọn aladugbo awọn.

O fihan ile ẹjọ wipe ni ọjọ keji oṣu kẹsan ọdun 1952 ni on fẹ iyawo on Iyaafin Doris Tourruno Melic.

Gbogbo awọn enia ti o wa ninu ile ẹjọ lo mi ori nigbati ọkunrin na sọ pe, Ọlọrun ko ti pese ọmọ kankan fun awọn lati igba awọn ti di tọkọ taya.

O wa rọ ile ẹọ wipe ki nwọn tu Igbeyawo awọn na ka, ki olukuluku awọn si ma a lọ ni ọtọọtọ, ṣugbọn adajọ sun ọjọ ẹjọ na siwaju. Bi nwọn ba siti parı rẹ si ẹ o ma a gbọ o.


Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street P. O Box 1495 Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M. S. Grammar School) Bariga Lagos (13/4/64)